E MA KA

IROHIN IMOLE

KI Ẹ SI MA POLOWO ỌJA YIN SINU RẸ. O kun fun irohin aladun, o si nkọ enia ni ẹkọ dada. O nfun enia ni oye.

# IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

AKIYESI

E ma ka iwe Irohin Imọlẹ nigbagbogbo nitoripe itan aladun meta kan yio bẹrẹ ninu ẹrọ laipẹ yi. Ekini ni itan Kọgbọn ninu eyi, orire ọmọ nbẹ lọwọ iya rẹ (apakini) itan igbesi aiye awọn ayaba ati awọn ọlọgbọn aiye (apakeji) itan igbesi aiye awọn ọrẹ meji oni-jibiti Eko ati Ọlọṣa Ilọrin (apakẹta)

VOL. I No. 28, WEDNESDAY 8, JANUARY — JANUARY. 14, 1958 KỌBỌ KAN


# E ko Nomba Nitori Arun Sopona

**Arun Sopona je eyiti o niberu gidigidi kakiri agbaiye.** Paapa, lati daruko re je eru jeje larin iran yoruba. Iberu yi lo jeki awon yoruba so o di Orisa akunlebo, kakiri ile Naijiria ni a ngbe mo arun yi, oruko ototo ni a si fi npe.

Hausa npe ni Adana, Awọn Ibo npee ni Kitipa, ṣugbọn orukọ mẹrin ni awọn Yoruba fi npee (1) Olode (2) Ilẹgbona, (3) Ọba, awọn orukọ mẹtẹta nwọnyi jẹ eyiti a nfi tọwọ-tọwọ pe ṣugbọn (4) sọpọna, nibikibi ti a ba ti pe orukọ yi, afara ko si, nṣe ni gbogbo awọn enia to wa nibẹ yio tuka yanga lẹsẹ kanna, ni toripe nwọn ro o si ipe ti afojudi

Olori awọn Onisegun Ilera (Medical of Health) ti ṣe ikede ni tori eyi wipe, ki olukuluku enia jọwọ ara rẹ lati kọ nọmba fun (Vaccination] ati awọn ara ile rẹ.

Ko nṣe wipe arun na ti kuku bẹrẹ. ṣugbọn ako nfi oju ogun wa ẹfọn, bi arun na ba tilẹ wọ ilu yio ba wa ni mimura silẹ de, ati pe lọdọdun ni a ma kọ nọmba fun gbogo enia bayi ni ibẹrẹ ọdun, nitori na ki ẹnikan maṣe taku wipe ṣebi mo ti kọ nọmba kan leṣi, ni torina nko tun ni ko lọdun ni mọ eyi ko buru.

Kọ nọmba fun gbogbo awọn ẹbirẹ, ati ọmọ titun ti o ba ti to ọmọ oṣu mẹta Bi enia kan ba ti kọ nomba lẹkan, osi tun di ẹhin ọdun mẹta ki o to kọ omiran. Ẹniti o ba ṣakiyesi ẹnikan ti arun yi wa lara rẹ, ki ẹ tete sọ fun awọn wolewole.


## SHOYINKA TUN GBE DE

Iwe Adura fun Arisiki lati Ilẹ Misirat 3/6d
Iwe Adura Akanse 3/6d
Iwe Ilana Esin Ojisẹ nla Muhammad 7/6d
Kurani Esumeta ti a tumọ si Yoruba 10/6d
Odu merindinlogun 10/6d
Iwe Aniyan ati Nofila Oru Osu Awẹ 5/6d
Iwe Egbogi Ajẹbidan 20/-
Itan Aladun 3/-
Gbedegbẹyọ Hausa 3/-
Ajiran Ilu Oku 3/-
Itumọ ala kikun ati Odu Ifa 12/6d
Iwe Owe Yoruba 3/6d
Psalmu Isẹgun Ajẹ ati aiye 17/6d pẹlu Turari lọfẹ
Turari Itaja 10/6d
Turari Ẹyọnu Ajẹ 10/6d
Abẹla Adura (Dragon Candle) fun Adura tete Dami lohun 15/-6d

Fi owo ransẹ si:-
J.O. SHOYINKA c/o Post Office Ebute Metta
Tab:
8, Ojo Road (Oduabọrẹ) Mushin,


## Mahmudu Dantata pe awon onigbese re lejo

**Kano**

Agbọ irohin lari ilu Kano wipe Alhadji Mahmudu ọmọ Alasan Dantata ologbe, ẹniti awọn ọlọpa ba ṣe ejọ larapa owo ayederu ti o ṣe, ti nwọn si kamọ lọwọ, eyiti nwọn ti torirẹ gbeju sẹwọn fun, wipe, o kọwe si Alikali, wipe awọn enia ti o jẹ on ni gbese pọ ati pe, nwọn le titori ọgba ẹwọn ti on wa ki wọn salọ tabi ki nwọn sọ pe nwọn ko jẹ on lowo.

Ogidinleje owo ti Alhaji na pẹjọ le lori to ọke kan pọun. Awọn Minister meji jẹ on ni £40 ati £50. Ọkunrin kan ni kano ya £750 ara Babure kan ya £50, ara Jegge £40, ara Anduruman £1,100, Alhadji Saro kan ya £8,350 Saro keji ya £700 ati ọpọ enia ti ko si aye lati darukọ wọn

## Awon Olopa beresi gbogun ti awon Omo ti o ti Sonu

### NJE OMO RE WA NINU WON?

Ọlọpa bẹrẹs gbogun nla ti awọn ọmọ ti o ti sọnu ati awọn agbalagba alairikanṣekan, ni ilu Eko.

Nwọn si mu to adọta awọn ọmọde ati to okun agbalagba ni apa ibi sọbu itaja. Ninu mọto awọn ọlọpa kan, awọn ọmọde bẹrẹ si sọkun ni orisirisi ede ti wọn nṣe alaye, tabi ti nwọn nsọ ọrọ ẹbẹ jade. Nwọn ko wọn lọ si ile ibi ti anpe ni Lagos Central Police Station ni ita Tinubu ni ibiti nwọn ti fi ika tẹ iwe.

Ki nwọn to bẹrẹ igbogun na, alagba alabojuto ti awọn ọlọpu, Mr. P. D. Milne sọfun oniwe irohin kan wipe ibi isẹ ohun nfẹ lọ la ti bẹrẹ igbapọ ti gbogbo enia eyiti yio le ju lori awọn ọmọde-kunrin ti nwọn nrin kakiri igboro ilu Eko ti nwọn nṣe bi ẹni wipe awọn alabojuto kẹkẹ ologere ati mọto awọn enia ti nwọn lọ ra nkan niuu sọbu lori wipe nwọn yio fun wọn ni tọrọ. (3d)

O wipe igbogun ti na bẹrẹ nitori iwa kuwa ti awọn ọmọ bẹrẹsi hu si awọn oni kẹkẹ ologere ati awọn oni mọto nitori awọn kọ lati fun nwọn ni ohun ti nwọn nfẹ.

Ọpọlọpọ ni awọn onikẹkẹ ologere ni nwọn ma nba kẹkẹ nwọn ni jijo, tabi ki nwọn tu agogo wọn kuro gẹgẹ bi iya nitori nwọn ko fun wọn ni iye owo ti nwọn gbọdọ fun 3d, nibiti awọn onimọto ma ba mọto nwọn ni bibajẹ tabi ki nwọn ti ji nkan lọ ninu rẹ.

# IMOLE

ESIN ORO WA: IMOLE DE OKUNKUN PARADA
*EDITORIAL WORKS & OFFICE*

16, Bamgbose Street, Lagos.
Telephone: 21985

*London Office—*
*Sunday Ayorinde:- 5, Hemming Street London E. 1.*

FUN OWO "IROHIN IMOLE" ODUN KAN
EKO—SILE MERIN KOBO MERIN (4/4d)
Ilu miran ni Naijria ati Oke-okun Sile mefa Kobo mefa 6/6d)


# ODUN MIRAN TUN DE

Awa oniwe Irohin Imolę ki yin lopolopo o ku alaja ọdun, ki Oluwa ko se ọdun na laho fun gbogbo wa. Awa gẹgẹbi orukọ wa, a ko ni fi dudu pe funfun fun yin, bęna ni a ko ni ri opiro ki a pe ni iro fun yin.

Ki a to tę siwaju ninu ọrọ wa, a ki awọn adari ilu wa yi pe wọn ku iṣẹ, Oluwa ko fi iṣẹ yin olukuluku wọn, ki Oluwa si tun ma fun wọn ni imọ kun imọ wọn.

Bakanna a kesi gbogbo ẹnyin ti ẹ ma nmu ọ̀rọ̀ i mu latin ilu, ti ẹ ma uso wire ọrọ ilu ko kan yin Ha! Arakunrin ati Arabinrin, awa oniwe Irohin Imọlę nfi ye olukuluku wipe ọnakọna ni ọrọ ilu fi kan ẹnikọkan wa, nitoripe olukuluku wa ni ero rę yato, boya ti iwọ ba sọ ero tirę ti gbogbo aiye ba gbọ yio jẹ iranlowo fun orilę ede wa; sugbọn bi ko sọ sita ko si ẹniti o le mọ ohun ti o wa ninu re, a ki gbo inu onikun mọ ika, toto o ṣe bi owe.

Gbogbo wa lo tę eti si ọrọ Olotu apapọ ile Naijiria Alhadji Tafawa Balewa nigbati o nki wa ka owo ọdun titun ti a ṣẹṣẹ bọ si yi. o sọ ninu ọrọ rę na bayi wipe aye wa fun olukuluku lati gbe ogo ilu rę ga nipa kikọ ẹdun ọkan rę sinu iwe Irohin ti o njade.

Pupọ ninu wa ni ko mọ ohun ti awọn iwe irohin jẹ, yio si jẹ ohun ayọ fun wa, paapa awa aro ilu Naijiria, ọpọlọpọ wa lo nfi iwe Irohin da agunla, a fę fi ye yin wipe iwe Irohin jẹ ohun pataki, ti ko ba si iwe Irohin a ko le ri Imọlę ni igbesi aiye wa, iwe Irohin kan, ainiye enia lo nka, ninu gbogbo iwe Irohin ti o si njade, ko si eyi ti Ijoba ko ki nfi oju ri. Nitorina ni o fi jẹ wipe ti o ba ri ohun ti Ijoba paapa ko ba ṣe dada, o le kọ sinu iwe Irohin, iba ṣe ni ede Oyinbo tabi ti Yoruba, ni dajudaju, iwọ yio ri iyatọ ninu ohun ti o fę ki Ijoba ṣe.

Nitorina ọdun titun ni a tun wọ yi, a ti gba ominira ti a ti npe ni ọdun meta, ti dirikai ni isisiyi, iṣẹ gidi lo si mbę niwaju wa, lomode lagba lo si ni iṣẹ ṣe, o si tọ o si yẹ ki a bere lati ibere ọdun yi, ki a ma sọpe asiko si wa fun wa, ara asiko ko ma duro de ẹnikẹni, iwọn ti ẹnikẹni ba ṣe la o sọ nipa tire.


DIRECT YOUR PRINTING JOBS TO:-

**MODUPE PRINTING PRESS**

16, Bamgbose Street.
Lagos.
Phone 21985


# IDAHUN SI ORO ADEWARA BALOGUN

Olotu,

Jọwọ gba mi laye lati dahun si ọrọ ọgbeni Adewara Balogun tio jade ninu iwe Irohin Imọlę oloyin mọmọ yi, ni ọna kedogbon osu to koja.

Akọkọ ọrọ mi si Ọgbeni Adewara nipe, awọn agbagba Ile Yoruba lonpa ni owe pe: "Ọmọ eru koni sai se ise Eru" beni ọrọ iwọ Ọgbeni Adewara yi je, on fi yewa pinu Iwe Irohin pe ki aimo kirun pomo wahalepo, ninu gbogbo Eku Oro Ilu wo ni Baba re ti je Balogun? Ati pe papa na, Baba re okoko je Balogun Ilu na ni, tio fi nfun ọmi iru Ilana tabi ọrọ aimogbon dope beyen?

Kini ninu mi bere iru Ibere meji yi ti ṣe, ni ati Imala ni awọn Baba-Baba wa ti mmọ Olorun papọ, boya igbati iwọ Adewara de Ile aiye ni ẹsin Islam de Eku Oro ni, kio laye mi, ti Alufa tioso fumọ wipe ti wọn ba nke Utuba ni awọn Ilu tio daruko ki ise ese, kioje ki nmọ, ati wipe papa na, boya Igba tio de Ile aiye si ni owa yẹ kia make utuba ninu awọn Ilu ti o daruko ni, sugbọn awọn agbalagba lonpa ni owe wipe "Ao lesọ wipe igbadigba Oyinbo, kia foju Egbo tele" sugbọn ẹni to ba nfę iresile Esin Islam Ọlọrun ni lati re sile ni.

Iwọ Ogbeni Adewara to ni ọgbọn to si ni lakaye lo ti nisọ pe Ijomu si Ọtun Oro je ibuso kan abọ Iludun sije ibu so kan, nje owa ni lakaye ju awọn Baba tobiọ lọmọ lo niyen, tabi nwọn ko mọ iye ibuso Ọtun Oro si Ijomu tele ati ti Iludun ni tabi nwọn ki kirun papo.

Sugbọn emi mọ dajudaju pe oni ise ọmọ bibiEku Oro rara, igbaro (ise oko) ni owo se ni Ekun Oro. Osi tun wawa mi gidigidi pe ki o wadi ni ọdọ enini oba wọsi ile re tabi eni ti on ba gbe ile papọ.

Ki won fa gbogbo bi isẹndale Eku Oro ti se tele ri wa, ti wahala fi wa pọ fun e nisinyi, lati malọ kirun ni Ọtun Oro, Irun Jimoh ati Odun, nkan ti ki ise ọjọ ọkan, sọ Jimoh ojọ meje tabi oni kioma lọ ki Asuba ati magari ni be ni?

Molẹ ti yẹ iwọ Ọgbeni Adewara dada ko si bere lọwọ Balogun to ni o bi ọmọ na, nje ni igbati oba Ọ̀roro wa ni agberun awọn Ijoye wa nlọ si Ibẹ lọpọn tin ọrun, tabi wọn ki ilọ? Agbẹrun sini yi to ibusọ mẹta abọ si Ọtun—Oro, ki ni wọn ko fi wa sọpe ojọn na pupọ ki awọn na yan oba ti awọn? Tabi bi ko basi isẹlẹ tio sẹlẹ, wọn ko wa ni malọ titi di isinyi ni "Sugbọn ẹni ti ko ba fi ọrọ lọ agba wo, kio to ma sọrọ iru re jade lenu, omugọ enia ni oyẹ kia kakun, owa nfi ye wa pe, Ebute-Mẹtta si Eko nkọ, "Alefi efi we Eda" bi Imale ti pọ ninu Ilu meji tio darukọ yi, bẹni owa wa ni Ijomu ati ni Iludun bi? Toripe okoro ọrọ Atunṣe ti owi wo rara ti ofi fọ lọ gbe fun oni Iwe Irohin.

Emi ni
Y. Ade Buraimoh
Ọmọ Ọtun Oro
Ninu Ẹsin Adinni

OLOTU,

Jọwọ gba mi laiye lati fesi si ọrọ Adewara Balogun eyi ti o jade ninu iwe yin oloyin mọmọ tise 25/12/57.

Modupẹ pupọ lọwọ Adewara lori alaye ti ose ati nipa ibere ti obere lọwọ mi. Emi Alufa Durosinmi ki ise ọmọ ilu Oro, ṣugbọn mo mọ ilu Oro dada ati awọn ẹku ilu Oro na, nigbati ọrẹ mi kan yio se iyawo molẹto ọsẹ meji nibẹ nipa ijomu ati iludun towi gbogbo rẹ ni momọ dada.

On pataki ti mo fẹ ki Mr. Adewara mọ nipe ọba kan lopa awọn ilu Oro na pọ, ati pe on ti Ọlọrun sọ ninu Alukurani nipe ki a to keri ilu ti wọn ni lati ma ki Utuba lọtọtọ, onilati je ibusọ merin [4 miles] okere gbaa ni on ti owa ninu kurani iyan bẹ, ki owa lọwo awọn ilu yi wo dada,—Oshogbo, Ilorin, Abẹokuta Kano, ati bebe ti o jẹpe wọn gun ni ibusọ merin tabi jubẹ lọ ọna kan na ni wọn ti nki irun Jimọh ati irun ọdun Ileya, kosi tun wadi wo dada niMecca ọna kan ni wọn ti ki irun Utuba

(Wo oju ewe kẹta)

# ỌMỌ IFE EKO SE ODUN EDDI

Irohin koto afojuba ni ere ajọdun Ọdun Eddi ti apapọ gbogbo ẹgbẹ ọmọ Ifẹ Eko se ni irọlẹ ọjọ Abameta ti iṣe ọjọ kọkandinlogun osu December 1957.

Ki o to to nkan bi agogo mẹrin irọlẹ, ni ẹsẹ gbogbo ọmọ Ile-Ifẹ Eko, Ebute-Metta, Shomolu, Oshodi, Idi-Oro, Mushin ati Agege ti pe sọsọ si ojude Oloye Denloye, ni 66, Kadara Street, Ebute-Mẹtta.



Ọmọ-Ọba Adeniran Adefarakan
Akọwe-Agba Ẹgbẹ Ọmọ Ifẹ Eko

Ere ajọdun yi bẹrẹ pẹlu orin alẹ-ilẹ lati ọwọ alagba Limọta Gboreti, ẹniti o jẹ Alakoso ati Amereya, pẹlu awọn Sanmọri Ọdọmobirin, Ọmọ Ile-Ifẹ, lehin eyi ni Iya-afin, Ogundimu (Iya-ẹgbẹ ọja Ararọmi) dide, o fi ọrọ iwuri ki gbogbo ọmọ Ifẹ to peju sinu apejọ na wipe, nwọn ku ewu Ọdun, ninu ọrọ rẹ, o ṣe alaye gẹgẹbi o tiṣe jẹ wipe, Ile.Ifẹ ni ipilẹṣẹ ilẹ Yoruba, o si pari ọrọ rẹ lori wipe, inu on yio dun pupọ ti ọmọ Ile-Ifẹ Eko, ba nba irẹpọ yi lọ bẹ, ati wipe, ki nwọn si tun fi ohun wọn ṣe ọkan fun igbega ati ilọsiwaju ilẹ Odudua na.

Lẹhin eyi ni, Oloye Denloye, Ọba-Ọfin ti Ile-Ifẹ ati Alakoso ajọyọ Ọdun na ki gbogbo ọmọ Ile-Ife to peju pesẹ sibi ajọyọ ọdun yi ku ewu ọdun, o si ṣe alaye iṣẹ nla ti Mọremi ṣe si Ile-Ifẹ, eyi to mu tọ'mọde ta'gba ọmọ Ile-Ifẹ, fi nse odun Eddi yi fun Iranti MỌREMI na lọdọdun.

Oloye Denloye, fi han agbarijọ ọmọ Ile-Ifẹ ọjọ na wipe, inu on dun pupọ nitori wipe, ọmọ Ile-Ifẹ, wọn ti nse ọdun Eddi l'eko yi, sugbọn ti ọdun yi dun pupọ. O ṣe adura fun Ifẹ ile ati Ifẹ idalẹ, o ṣe adura fun ẹmi gigun Ọba Aderẹmi, o pari ọrọ rẹ lori orin yi:-

> Ọba a tẹrẹrẹ K'aiye
> Kabiesi O! Odudua
> Orisa idalẹ Ifẹ
> Odudua, Olofin O

Lẹhinna ni jijẹ ati mimu bẹrẹ si kọlu ara wọn, ti onikaluku bẹrẹ si jo ijo ajọsọdi, ti gbogbo rẹ bẹrẹ si dun yungba titi di nkan bi agogo mẹwa alẹ.

Diẹ ti a ri aye darukọ ninu awọn agbalagba ọmọ Ile-Ifẹ to peju sibi ajọdun na niyi:- Oloye Ọba-Ọfin Oloye Ẹlẹmọrọ, Rufai Giwa Awoyejọ, S. Banirẹ, Phillip Arawumi, Gaibrel Adewumi, S. Showale, Abasi Igedi, S. Akinfala, Ọmọ-Ọba Adetunji Shijuade ati ọpọlọpọ gbajumọ lọ'kunrin ati lobinrin.

Bi Oluwa ba da ẹmi gbogbo wa si, laipẹ yi ni ẹnyin Onkawe yio ri iru iṣẹ ti Mọremi ṣe si Ile-Ifẹ ka eyi to mu ki ọmọ Ile-Ifẹ maa fi ọdun Eddi ṣe Iranti rẹ lọdọdun.

Ẹnyin Onkawe, ẹ foju sọna o.

# AROFỌ ANỌYINLOHUN
## IKU To! To!! To!!!

Iku ọjẹgbẹ onikọ
A gba'pa lọwọ Akẹran
A de k'agbẹji s'ado mu
A de k'awo dogberi
Iku sọ'le aladun
Di ibi awonu
Ẹnyin ara Eko ẹ ko gbohun mi na
Emi Anọyinlohun-bi-ọmọge Imaro
Mo gbọ'ku Randle
Mo tu puru sẹkun
Iku ko m'olowo Iku ko motosi
Iku akodu ya mi lẹnu
Iku fẹsin silẹ o m'ẹlẹsin lọ
Iku kọ popijẹ
Iwun iku yi nfẹ saiye da
O ṣebi o ye mi na
Iku tun fo fẹrẹ o wole to Silva lọ
O gbe jagun lọ loriyẹ
Silva adu-ma-dan ape ọmọ Afiwa pẹsẹ
Onile oke yi nwun ọlọrọ
O nwun ọmọ otosi
Ẹnyin ara Eko
Ẹ ko nwoye na
Ejiwunmi tun gba waya
Iku mu jagun lọ
Si Paradise oke
Tọmọde tagba re nfẹkun
Ṣe 'daro rẹ o o dẹ digba
Nwapa tun yẹri bẹsẹ
O fẹru silẹ lọ
Jagun rẹhin ẹku
Iku kọ mọ oṣelu
Ko mọ onilẹ
Ko mọ ẹni rowo jẹ kuta
Ko mọ ẹni nfẹfọ jori
O ma pọ kẹ
Iyi mọ ti nwi lateni
Mo simi mo dẹhin ọrọ
Iku mẹ re sa pa baba mi
Iku ko gb'etutu
Emi ku ti ṣẹbọ tan
Awa yi ku a ku ewu
A ku ajaiye
Kolukuluku ṣa ma palẹmọ ọrun
Iku mbọ lọna
K'a ma ku 'ku ina
K'a ma ku 'ku omi
K'a ma fi gbese sọrun ọmọ
K'a i pẹhinda

# A. A. AKINSOLA S'OKU IYA RE

Irohin ko to afojuba ni ti isinku iya Ọgbẹni wa A. A. Akinsọla ti o ngbe 34, Ọlọnọde Street, Yaba Estate ṣe ni agbo-ile ẹlẹgba ada ni Abẹokuta, ẹsẹ awọn ẹnia jankanjankan lati Eko ati ọna jinjin pe sibẹ. Nṣe ni Gin npe Beer ranṣẹ, Ogurọ ati Stout ko tilẹ ribi duro si, amutakiti ni awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na nmu.

Odindi malu bọsa ni Ọgbẹni yi pa. Diẹ ti aye wa fun wa lati darukọ sinu iwe yi ni awọn Ọgbẹni J. O. Folarin, Idowu, J. S. Blaize, Makanjuọla, Ṣoyọye, Jaiyeọla ati Olumide



Madam Akisọla

Laisi. Iya Ologbe yi jẹ ẹgbọn fun iya Ọgbẹni wa J. O. Shoyinka. Iya wa Atunwa ọrun rere o!


# Afose Isedale Yoruba
## ATI PSALMU AJEBIDAN

IWE YI WULO NI ONA PUPO

1. Ofọ atata fun Arisiki
2. Ofọ atata fun Madarikan.
3. Ofọ atata fun Itaja
4. Ofo ti ki jẹki ope tan enia
5. Psalmu Ajẹbidan fun Ẹyọnu Aje.
6. Psalmu fun Orire
7. Psalmu fun ọja tita
8. Psalmu Ajẹbidan fun Madarikan
9. Psalm Ajebidan fun idabobo lọwọ Ajakalẹ arun.

Irohin ko to afojuba ti o ba ni iwe yi lowo, o ju Wura ati Fadaka lo.

EYO KAN 2/6

DOSINI 20/-

Fi owo ranṣẹ si:-

POPULAR BOOKSHOP
c/o Post Office, Ebute-Metta.


# IDAHUN SI ỌRỌ ADEWARA BALOGUN

O bẹrẹ lọjú ewe Keji

bi on ti mowi yi koba da ẹ loju, ki o lọ wadi wo ni ọdọ awọn toni mimọ ti wọn ba sunmọ ẹ dada.

Nipa ti ilu Eko ti o wi ati Ebute Metta ti o ṣe apejuwe wọn, o yatọ pupọ si ti ilu Oro, agidi ni awọn ara Eko nlo, ki iṣe mimọ ni.

Emi ni
ALUPHA DUROSINMI

